# IDANWO HALT-IT NAA

## ALAYE NI ṢOKI NIPA IWADI NAA

Haemorrhage alleviation with tranexamic acid - Intestinal system

**Tranexamic acid fun itọju ẹjẹ ti o nda lati inu ifun ati ikun: ohun agbaye aimunişişẹntẹle, idanwo iwadi itọju ti o farasin fun olutọju ati alaisan**

Ẹyin (alaisan naa) ni ẹ̀jẹ̀ ti o nṣan jade lati inu ifun ati ikun yin wa ti o nilo itọju ni kiakia. Gbogbo itọju ti a sábà maa nṣe fun ẹjẹ dídà ni ile iwosan yi ni a o fun yin. Pẹlu eyi papa, A npe yin pe ki ẹ wa kopa ninu iwadi kan. Iwadi yi yoo ṣe ayẹwo boya ogun kan ti a npe ni tranexamic acid lee din iṣẹjẹ inu ifun ati ikun kù. Ani ireti pe lilo ogun yi yoo ṣe okunfa iwosan ti o dara si. A mọ wipe ogun yi nran awọn eniyan ti o ni aisan iṣẹjẹ miran lọwọ ṣugbọn a ko ti mọ boya o nṣiṣẹ fun iṣẹjẹ lati inu ifun ati ikun.

Ninu iwadi yi, ìdajì awọn alaisan yoo gba itọju ti a nṣe iwadi rẹ (tranexamic acid), idaji yoo si gba itọju ti o jọọ (itọju ti ko ni ògùn naa ninu). Ti ẹ ba kopa ninu iwadi yi, ẹ óò gba Itọju ti o ni ogun iwadi yi ninu tabi eyi ti ko ni ninu lẹsẹkẹsẹ. Ẹ óò gba si ara lati inu omi ti a o fa si yin lara fun wakati mẹrinlelogun (24 hours). A tun nilo lati gba awọn alaye nipa ipo eto ilera yin (alaisan naa) ki a si fi ṣọwọ́ si ọfisi nla wa ni ilu Lọndọnu.

Ti ẹ ba nifẹ si ati mọ siwaju si nipa iwadi wa nisinsinyi, a óò sọ fun yin. Bibẹẹkọ a óò sọ nipa rẹ siwaju si nigbamiran. Njẹ ẹ faramọ pe ki a tẹsiwaju nipa itọju iwadi yi bi?

**Bẹẹni, mo faramọ pe ki ẹ tẹsiwaju.**

| ______________________________ | ________________ | _________________________________ |
|---|---|---|
| Orukọ Alaisan tabi aṣoju | Ojo | Ibuwọlu (ìtẹ̀ka tabi ami miran ti ko ba le kọ̀wé) |

*[Ẹ le ṣe alaye pẹlu ọrọ ẹnu ko si nilo pe ki o jẹ akọsilẹ inu iwe gerege. Ẹ le yí akọsilẹ yi pada ki o le ba ipo kọọkan mu, ati pe a ṣe ipese akọsilẹ yi lati jẹ gẹgẹbi atọna. Fọmu ti a bu ọwọ lu ki iṣe dandan, ti wọn ba si buwọlu, ẹ ko gbọdọ ri gẹgẹbi ifohunsi atọkanwa ti o ni agbara.]*